AKIYESI

Ka Irohin Yoruba ni ọsẹ ti mbọ fun agbaagba egilamọ ọrọ agiri lati ọwọ "Ọmọ Oduduwa". "Ọmọ Oduduwa" yio fi gege wura ẹ da oira ninu upakeji iwpaya rẹ. Mase padanu anfani iyebiye nitori owo pọpọ.

Irohin Yoruba

NO. 98 WEDNESDAY JAN. 29—TUESDAY FEB. 4 1964 KOBO META 3D

Ọrọ agba

OPERẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbaje. Otito d'oja o kuta, owo lowo la nreke; otito ni bori iro nikẹhin.

PASAN TI A FI NA IYALE WA NI OKE AJA FUN IYAWO

PAGA, AGBAJE ṢUBU !

Ijọba Akintọla fẹ tuka?

Ọrọ ayamosepo ijoba egbe Alakuko ati egbe UPP ni Ipinle Iwo Oran di imo tu imo jo, imo enini ki i dale" ni ojo Ojobo ti ise ojo ketinlelogun osu kini odun yi nipa yiyo ti nwon yo Oloye Mojeed Agbaje kuro ni ipo Minista Alakoso eto Irohin ti o se fun osu merin pere.

Egbe Alakuko so ni Ibini laipe yi pe yiyo ti nwon yo Oloye na yio mu won da Ijoba ajumosep awon mejeji ro laipe yi.

Alaye ti o jade lati

OLOYE AGBAJE

ile ise Olo o Ipinle Iwo-Orun lori iladuro Minista na ni pe, awon fẹ le ofin ati ilana Ijoba Ipinle Iwo Orun lati se bọ ọ ni. Nwon ko si so idi kan ti nwon fi daduro.

Oloye Agbaje se gbadugudu meje ninu rogbodiyan ti o sẹlẹ si Egbe Alakuko ni Ibadan. o si je igi lẹhin

(Wo oju ewe kẹjọ)

ODUA KỌ ỌLỌFIN

Igbimọ Alabẹsẹkẹle Apapọ Egbe Ọmọ Oduduwa ti so ninu ipade kan ti nwọn se ni Iperu ni ojo Abameta ti ise ojo kejidinlogun osu kini ọ̀un yi pe awọn ko ni se ohunkohun pelu Egbe Ọmọ Ọlọfin titi akoko ti Ajọnla egbe na yio fi ni ọrọ lori egbe titun yi.

Nwon si se ipekasi akosile ofin egbe na eyiti o fihan pe ninu Ajonla nikan ni awon ti je se ipinnu lori iru oro ti o ba jobi be.

Ipade Ajonla egbe na yio si waiye ni ojo kokanlelogun ati ikejilelogun osu keji odun yi.

Awon die ninu awon ti o wa si ipade igbimo Alabesekele na ti nwon se ni ile Oloye M. A. Okupe ni Ipera ni:— Ogbeni R. A. Jagun, Iyaafin A. Peters, Emowa E. O. Aiyejunde, Oloye Nunru Alade, Oloye A. M. Adebule, Oloye S. T. Osoba, Ogbeni J. C. Ebeda. Oloye Iyaafin Somilola Osoba, Ogbeni Johnson O Oniosore, Omo'ba Adeboye Adefarakan, Omo'ba

(Wo oju ewe kẹjọ)

Ike ni epin odun gbogbo Egun ni o fi omo enia gun ko si le se alaye. Aworan oke yi fi opin alikanju ati akoni enia kan han. Wo aworan na, ki o tun tunwo. Iranku Ologbe Shonibare ni ise. Fun ekunrere aworan ati aohun ranka Ologbe S. O. Shonibare, wo oju ewe kerin ati ikarun.

AWỌN AGBẸ NFẸ IDIBO

Igbimo egbe Agbe ek a Ibadan ti se ipinnu kan albi ipade ti egbe na se lenu loloyi pe ohun ti o kan nisisiyi nipe ki awon to Ijoba ajumose egbe Olumolangidi ati Alakuko Ipinle Iwo-Orun ka ni klamosa.

Nibi ipade na, awon agbe so pe ibo didi ni o le yanju ede aiyede ti o wa ni Ipinle Iwo-Orun Naijiria nisisiyi.

Awon egbe na ni awon nyakiyesi gidi nipa ọrọ awon agbe ni ojo iwaju, nwon so bayi "gbogbo iye owo awon nkan oko ko le ti bọ sele bi a ba tile mu ikore ti ko pe saaan sọ".

Egbe Agbe wa kesi awon ti nse Ijoba ni Ipinle Iwo-Orun Naijiria ki nwon lọ bere aye titun lowo awon adibo ki awon oniowo okere tun le ni igbekẹle ninu wa lẹkan si."

ISIMI ỌDUN IMALE

Ikede fi ye g b o g b o awon enia lati ile ise Ijoba Apapo ni ojo 'Ru ti ise ojo kejilelogun osu kini odun yi pe :

Ojo Eti ti ise ojo kẹrinla ati Abameta ti ise ojo kẹẹdogun osu keji odun yi yio je I s i m i odun Ipari Awẹ 1964.

Ojo 'Ru ti ise ojo kejilelogun ati ojo 'Bọ ti ise ojo ketalelogun osu keta odun yi je isimi fun odun Ileya nigbati ojo kokanlelogun osu keje odun yi ti ise ojo Isegun yio je isimi ojo Ibi Anọbi Mohammed (Nabbyi Lawal).

AKINJIDE T'ỌRUN BỌ GBONGBO

Ogbeni R. O. A. Akinjide ti terun bo gbongbo Ogbeni F. S. McEwen nipa aposebete oro lori apapo Igbimo egbe Alakuko eka Ibadan ka.

Ogbeni McEwen ni akọwe arapọ egbe Alakuko o si ti bu enu ẹtẹ lu ọrọ Ogbeni Akinjide eniti ise akọwe I g b i m ọ egbe na ni Ipinle Iwọ-Orun pe "o nwa ona lati yi ọrọ rogbodiyan na mọ ori Ikorira eya ati igbe ọta si ara eni.

Ninu ikede ti o jade lati ilu **Eko ni ojo Isegun** ti se ojo kokanlelogun osu kini odun yi lori bi nwon ti se yan Ololа Mbadiwe lati je alaga awon ti yio se atunse egbẹ Alakuko Ibadan, Ogbeni McEwen so pe 'gbogbo awon ti o mọ egbe Alakuko ati ise won yio gba pe eleyi je asa egbe na lati ma yan asiwaju Ipinle kan si Ipinle miran nigbati Ipinle ti oran na ba kan ba ti fihan pe nwon ko le se atunse awon eto ara won ona ti o dara

RICHARD AKINJIDE

Ogbeni McEwen wa se atako ọrọ O g b e n i Akinjide bayi pe "Pelu

(Wo oju ewe kẹjọ)

Ogun Ibo ni Alakuko

Ogbeni G. A. Eze ti ise bahasale egbe "Ibo State Union" ti so gbangba nigbati o npolowo Ibo pe, ogun ibo ni egbe Alakuko. O ni ki awon enia Sapele pejulo awon ibo darapo sokan dibo fun egbe Alakuko ninu ibo Agbedemeji Ipinle Iwo Orun ti nwon fe di laipe yi.

Baba egbe na so pe awon ko ni gba egbekegbe laye lati timu bole da egbe won ru. O si fowosoiya pe ipapo MDF/NPC lati dibo ni agbedemeji Ipinle Iwo Orun ko le mu abayọ-isi rere wa bikose ikuna ninu ibo na. Ogbeni E z e fowosoiya pe NCNC ni yio wole mo-ke ninu ibo na.

IMULE

Ogbeni Eze ni egbe imule patapata gbaa ni NPC atipe nwon ka Ipinle won kun ju elomiran lọ. Igberaga yi ni ko jeki nwon tile da-ba lati se ipade ajo nla egbe won ni iha Gusu Naijiria.

Oloye Sunday Odjie ọmọ egbe Alakuko ti o jatile ninu ibo gbogbo-gboo ni iha Iwọ Orun Urhobo paapa ba ipade na sọrọ. O gba awon enia na n' iyanju pe ki nwon dibo kikun fun NCNC nitoripe bi awon ba wole ibo na won yio ni anfani lati si Minista atipe ti eku ida Ijoba ba bọ si NCNC lowo, gbogbo awon nkan idagbasoke ti o ti nje won ni iya ni yio to won lọwọ.

LAILEGBE LAILEGBE LAILEGBE

Aye-e ti ogborin julo

Ni kukuru, an rei awon nkan Odun tinun, Apere iri-ri SKODA OCTAVIA (Moto Ayokẹle) titun ti 1964.

Sugbon asi si awon (Moto Ayokẹle) SKODA OCTAVIA ti Odun 1963, ati wipe ati se eto lati ta won ni kọja nle pelu odinwo repete.

O je ipinnu ti ogborin julo ni odun titun ti asi fun gbogbo enia asi i t u n se ileri wipe awon eroja ara ẹ (Spare Parts) ati amo je to gidigidi yio wa ni gbogbo igba.

Se ipinnu re lati lọ ra tire nibikibi ti awon ile ise wa-wa.

G.L. GAISER (NIGERIA) LTD

APAPA	— 27 Creek Road
EBUTE-METTA	— 35 Glover Street
IBADAN	— New Court Road
KANO	— Manchester Road
JOS	— Queen Elizabeth's Way
PORT HARCOURT	— 3 Station Road
ONDO	— c/o Flonis Brothers Ltd. Ondo Odibo Street, Ondo.

LAILEGBE LAILEGBE LAILEGBE

ORỌ OLOTU

IRONU WERE (3)

NIGBATI ẹgbẹ Alakukọ wa ni ẹgbẹ Alatako ni Ipinlẹ Iwọ Oorun Naijiria ki nwọn to fi eru gba Ibukun, ẹgbẹ na fọnnu pe ko si ohun ti awon ko le ṣe bi awọn enia Ipinlẹ Iwọ Oorun ba fun wọn ni ayọ lati ṣe ijọba. Nwọn sọ paapa pe awọn le ṣe oke di ile ati ile di oke, ẹugbọn gbogbo ohun ti o ṣẹlẹ ni Ipinlẹ yi bayi ti jẹri si pe ẹgbọn ati Isakaṣe wọn ko pe iye to lati gbe ipinlẹ na. Nwọn ti kuna lleri nwọn si ti ṣe wọn lọhin.

Nje ẹgbẹ Alakukọ yi kanna kọ ni o ṣe ileri fun awọn enia Ipinlẹ yi ni igba ikẹ pe bi awọn ba gba ijọba, owo ori ninan yio de opin? Ni igbana, ẹgbẹ Afenifere so pe ileri omugọ ni eyi ise. Awọn enia ti o gbọ nigbana ko ni gbagbọ rara si ẹgbẹ Afenifere bayi. Awa bere pe abọ ileri ẹgbẹ Alakukọ ha da? Tabi owo Yoruba kọ ha ni pe 'oju ti yio ba enia kalẹ ki iti owuro ṣe ipin? Ibẹrẹ ijọba Alakukọ ni Ipinlẹ Iwọ Oorun fihan pe ko le ba ipinlẹ yi kalẹ. Awọn omolẹhin ẹgbẹ na ko gbagbọ ti mọ eyi paapa ki a to tọka si.

Awọn enia Ipinlẹ Iwọ Oorun iba ṣe mọ pe ẹgbẹ awọn ohanna enia ni ẹgbẹ Alakukọ ti ko ba je iwa ọdalẹ ti ẹnikan ko ni ẹgbẹ Afenifere, ti akuko si gbe ogbe ori ọ̀ fun kolọkolọ je? Ngota, ago ta, okiti obẹ ni ẹgbẹ Alakukọ pe e. Ẹugbọn eja ti di ejo si wọn ni apo, alara si di idaro si wọn ni ọnu. Iwa ohanna ati aimo Olorun ti ṣọ akoso ijọba di oku aparo mọ wọn lọwọ. Yoruba ni ki a ti ibi ọna kiyesi si ogun. Ṣe eniti ka le ṣe akoso ẹgbẹ ọ̀ dandan ni yio ṣe akoso ijọba itura ati irọrun? Ogun lonii, ija lọla. Ki a fi mọ ni iwọn nilati ọ̀ pe ẹgbẹ na ti teka ni Ibadan, Ekẹokuta, Ilesha, Akure ako? Ẹgbẹ na ko ha ti ko owo ori ti nwọn gba ni Ado Ekiti je?

Awọn omọ Yoruba ti o ṣẹku sinu ẹgbẹ Alakukọ gbodọ ronu jinlẹ gidigidi bi o ba je wipe ire ati anfani Ipinlẹ Iwọ Oorun ni nwọn nfe. Iyipada si rere wo ni o wọ Ipinlẹ yi lati akoko ti ẹgbẹ Alakukọ ti paṣẹpọ mọ awọn ọdalẹ lati tayo ekute ati ologbo? Kaka ki o dara si, nṣe ni o nbajẹ si. Anfani wo ni o ha wa ninu orogbo? A pa ko lawẹ, a bu u je, o koro. Awọn omọ Yoruba ko gbodọ pa ẹgbẹ yi ti ni ni? O ye ki awọn omọ Yoruba mọ dajudaju pe orisa oke ti ko ba le gbe en a gbodọ fi Oluwa silẹ ẹẹẹ bi o ti ṣe ba a. Ko ha buru jai pe ẹgbẹ Alakukọ ko le tun ohunkohun ṣe ju ki o ba a je lọ.

OHUN ti ẹgbẹ Alakukọ ti tẹnumọ lati ibẹrẹ ọdun ti o kọja yi nipe awọn ase "ise atunse" ki eni pe ohunko kun bajẹ. Abọ atunse naha da? Ẹniti o fi ọdun meta pilẹ were, ọdun melo ni yo wa fi sinmi?

OHUN kanṣoṣo ti Irohin Yoruba ri ko ju ki awọn ohanna kan ma kigbe Pawa! Pawa!! Pawa!!! kakiri igboro bi aja ti o ja ni ori iso. Ko ni ya awọn en a lẹnu lati gbọ wipe oganlogọ ninu awọn enia wọnyi ni aisan warapa tabi giri ti fi ara wọn ṣe ibugbe. Nwọn a na owọ soke bi enigiri nigbati nwọn ba ndahun si igbe Pawa! Pawa!! Pawa!!! Pawa ni awọn mẹkunnu fẹ je ni tabi ti nwọn yio fi ṣe ayọ bora? Aisan giri ni o wu lara awọn enia ti nwọn npe ni Pawa. Bawo ni ori amugbo ṣe le pe to lati jirorọ lori iloniwaju awọn mẹkunnu?

Bi ko ba je wipe kiki awọn omugọ ni ise aṣiwaju ẹgbẹ Alakukọ ni Ipinlẹ Iwọ-Oorun, awọn omọ Ibo-Ibadiwe ati Okafor ṣe le wa ma pari ije fun wọn ni Ibadan? A ti ṣọ bẹ tẹlẹ pe ẹgbẹ Ibo ni ẹgbẹ Alakukọ nwọn ranti bi omọ alenda. Okeẹ ko ha ti gun ori ireke fun oju ọlọde lati da? A kesi awon omọ Yoruba lati yago fun ẹgbẹ ti ko ni olori. Omọ Yoruba melo ni orukọ wọn nje Nbadiwe ati Okafor?

A ba tafa ọrọ lu ẹgbẹ Omọlangidi bakanna ẹugbọn nwọn here si nyamba nitoripe apo Oloye Akintola nikan ni ẹgbẹ ti o nje UPP wa. A kesi awọn adibo pe nigbati akoko na ba de fun wọn lati dibo, nwọn ko gbodọ gbagbe wipe ẹgbẹ Afenifere ti ijọba tire da ile iwe ọfẹ silẹ, nwọn yọ oda si oju ọna mọto, itura ati irọrun wa nile ati loko, ẹugbọn ẹgbẹ Alakukọ ti ijọba tiwọn yọ Oba ati ijoye nwọn le awọn ọpọ kuro lẹnu ise, alarinkiri pọ jara bi omọ yansila, owo ko si, ise towọn, oja kuta, irorun ati ifeyabalo ko si.

IRONU were ko ha ni lati fi wura lọ siede wa tabi fi agbọn lọ oiye wo? Botaki ije enje fun obe. Awon adibo gbodo kiyesi ara gidigidi. Awon ohanna tun nmo lati fi eru gba Ibukun. A o pade lese awon adibo.

Alapara Ibadan

Alapara: Ẹ ku owuro Olotu, ṣe dada lẹ ji loni o?

Olotu: Ẹ ku oye yi o Alapara. Ṣe o ri o?

Alapara: Nko ri Olotu nitoripe mo ti ṣ. ogun otutu oye ki ngto jade ni ile.

Olotu: Kini ogun otutu oye o? Dakun maṣai juwe re fun mi o.

Alapara: Ogun na ko

ALAPARA IBADAN

le daninidanin Olotu; Iwẹ owuro kutukutu hai ni ogun oye nitoripe bi enia ba ji we lowuro kutu hai tautau ni oye yio gbonnu.

Olotu: Mo gbadun ogun re na, otito ganan ni, emi paapa si 'ti nsa iru ogun bẹ e tipẹ, ti o si ti nje,

Alapara: Aṣe eda ti ko ba kan mọ ni iwọn, oju re yio ri orisiriṣi nkan Olotu.

Olotu: Kini oju re tun ri o?

Alapara: Ni ojo Aiku ti ise oj kẹjila osu kini ọdun yi ni mo 'bẹrẹsi digbẹrẹ lọ lẹba eti okun l'Eko, nko iti rin ju ọna bata mẹjila lọ ti mo ti bẹrẹsi ri orisiriṣi lrlri.

Olotu: Iriri bi bawo o, Alapara?

Alapara: Mo ri awọn obinrin abilekọ ati Wundia 'gontogonto ti wọn niuwe nilu okun, omiran pupa, omiran ẹnuu, ni kukuru irisi gbogbo wọn fa akọ mora. Ki ogma puro tan nyin je Olotu, mo tẹjumọ mọ wọn titi gbogbo wọn fi dojubomi 'Nwọn si kigbe le mi leri pe kini baba oniranu yi ṣwo?

Olotu: O ko ya fọṣọ fẹ ẹ?

Alapara: Nko le fọṣọ fẹ bẹ ẹ" nitoripe Kini yen ti ba mi dele dedẹdẹ nigbati mo f'oju kan awọn abo na, ayafi igbati nwọn fọn omi simi lara ni mo to yi ẹṣẹ

Olotu: Ni kukuru ni oba fi odọ wọn silẹ pelu gidimokai?

Alapara: Bẹẹni 'Olotu, a se yiyi ẹṣẹ ti ngo yi ẹ.' pada pabambari obirin ni ngo tun lọ bi pade

Olotu: Ọrọ obinrin ti o nji so lowuro yi ko ie mi lọrun, dakun lapara if ko ba si ọrọ miran ti a le tun ṣọ, iba dara ti a ba fi ọrọ yoku di ọṣẹ to mbọ lagbara Olorun

Alapara: Odara o, Olotu ki ngto ma a lo, ma ro pe inu awon onkawe mi y'o dun lati ri aworan oke yi, Ara awon aworan ti mo mu bo wa lati okun lati fi ta oju won lọre niyen.

IBADI LAIYE WA

Olotu: Aworan obinrin na da.a, arimubelẹ, a wo pada ẹhin ni,

Alapara: Ẹ wo bi irun ori re ti nkan ni baradi bi ti tarubawa. O ngba oju feere bi ayab SOLOMONI

Olotu: Emi paapa ri bẹẹ, dakun ki a pa ti awada ti Alapara o' Inrin na ko yeki o ni ruko meji ti o yeki o ma je ju IBADI LAIYE WA. Ka fi ire pade o Alapara.

Aworan oke yi ni ti obinrin kan korobosi ki oka ibadi laiye wa arimalelo awopada ẹhin l'awon okunrin gidi.

TABI IRORA OJU EGBO

Nigbati afọju bafẹ ti eni ngma ki eje egbo Ara mase e ti o si tun nsan e, ri daju, ati wipe oti Ipara Mentholatum pa daradara. Iwọ yio ri iyanu, ati Igbaduo iwosan kiakia. Mentholatum ngma ki awọ ara dẹ, dan, otun ngma ara da. Agbegasa, agbegasa Mentholatum, o dara fun awọ re.

ATURA—TAWỌSE—IWOSAN

Jẹki Mentholatum ma wa ninu ile re nigbogbo igba—za ide tabi Agolo kan loni BERE FUN OJULOWO MEN-THO-LA-TUM

MENTHOLATUM

OGUN IPARA TI O DARAJULỌ

Awọn ti o nse ni Mentholatum Company Ltd. (Est. 1889) Slough, England.

'Ọbẹ' tu Ẹgbẹ Okpara ka

DOKITA OKPARA

Iparun ti de ba ẹka ẹgbẹ Okpara Youth's Brigade "Ibadan, nwon si ti yan alakoso kamaṣọ ti yio tun gbe ẹgbẹ na dide ni ona akotun eyi ni ikede ti o jade ni Ibadan ni ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu kini ọdun yi

Maduro fun igba diẹ si ti de ba Ọgbẹni Murani Aralamọ ti iṣe akọwe ẹgbẹ na nitoripe o sọrọ odi si Oloye R. A. Akinyẹmi ti iṣe baba isalẹ ẹgbẹ ẹgbẹ na.

Ọgbẹni Aralamọ sọ ni ọjọ isegun ti iṣe ogunjọ oṣu kini ọdun yi pe ẹka ẹgbẹ on ko faramọ ọrọ ti Oloye Akinyẹmi ni pe ki Dokita Okpara yọ Ọgbẹni Richard Akinjide ti iṣe akọwe igbimọ ẹgbẹ NCNC Ibadan kuro ninu ẹgbẹ fun iwọn igba diẹ.

Oloye Akinyẹmi tun sọ siwaju si pe, ki awọn ṣe iwadi kikun nipa iṣe iṣele Ọgbẹni Akinjide ni Ipinlẹ Iwọ Orun, ti nwọn ba si ri pe on ojo NCNC lọṣẹ, ki nwọn da duro.

Alaye ti Ọgbẹni Aralamọ funra rẹ ṣe nipe, isoro ati isesi Oloye Akinyẹmi ko mu ọmọluabi dani. O ni ẹgbẹ ko bẹ Oloye Akinyẹmi lọwẹ nipa gbogbo ọrọ afafasun ti o mọ, ninoripe ghoninghoin ni awọn wa lehin Ọgbẹni Akinjide, o si tun fi kun pe ifaramọ imọran Oloye Akinyẹmi ni lo da ẹgbẹ NCNC ru ni Ibadan.

Nina ipade pajawiri ti awọn ṣe ni ọjọ Ru ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu kini ọdun yi ni nwọn ti pari ẹka ẹgbẹ Okpara Brigade rẹ, ti nwọn si yọ Ọgbẹni Aralamọ Ẹgbẹ.

EKITI GBODO DI OPO ISOKAN MU

Alaga ẹgbẹ ọdọ ọmọ Ekiti (Ekiti Youth Union) Ọgbẹni J.D. Fapohunda ti kesi gbogbo ọmọ Ekiti l'ọkunrin ati lobinrin pe ki nwọn duro sinsin fun iṣọkan ati aṣepọ ile abinibi wọn Ekiti ni pato ati orilẹede Naijiria lapapọ.

Alaga na sọ eyi ni ipade ẹgbẹ na ti nwọn ṣe ninu gbongan Ile Ẹkọ giga Ibadan Boys High School Oke-Ado Ibadan ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu kini ọdun yi.

Ọgbẹni Fapohunda sọ ṣaju ninu ọrọ rẹ pe, ohun ti o le tun jẹ anfani ati ilana itesiwaju fun gbogbo ọmọ Ekiti ni iṣọkan gbogbo ọmọ Ekiti.

Ki gbogbo ọmọ ẹgbẹ to dide fun ipade ọjọ na, awọn ọmọ ẹgbẹ Ibilẹ Ekiti kü ṣe ẹgbẹ oselu tara yan awọn oloye ẹgbẹ fun ọdun ti a wa yi.

Ọgbẹni J. O. Fapohunda, Alaga, Ọgbẹni Fẹmi Olushakin,

Igbakeji Alaga, ogbẹni E.O.Olofin, Akọwe Ọgbẹni Adelugba, Akọwe Ọgbẹni Akọsile, Akọwe Amegbedun; Ọgbẹni Ayọ Olaniyi Akọwe owo, Ọgbẹni Ayọ Anjorin Akapo Ọgbẹni Oye George ati Ọgbẹni Fagboun Ayẹwe owo; Jọla Ogun lusi Akọwe Ikede ati ọgbẹni C. A. Atoki, Amofin ẹgbẹ.

Bakanna ni awọn ọmọ ẹgbẹ na si yan Elekọle ti Ikọle Oba Adetunla Adeleye keji Ogoga ti Ikere, Oba Fabikun, Ọgbẹni Olawumi Fọladun Igbakeji Olukọ agba ti ile iwe giga Ibadan City Academy, Ọgbẹni J.B. Omotọsho, Agbẹjọro kan ni Ibadan ati ọjọgbọn J.F.A. Ajayi ni babasalalẹ ẹgbẹ na. Nwọn si yan Iyaafin F.A. Babatọla ni iyaẹgbẹ.

Ọgbẹni Olawumi Falọdun ọkan ninu awọn babasalẹ ẹgbẹ na ti o wa si ibi ipade na gba awọn ọmọ ẹgbẹ ni iyanju. Ninu ọrọ rẹ o fi gbolohun ọrọ yi fun ire ilẹ wa siwaju awọn ọmọ ẹgbẹ gẹgẹ bi ohun ti nwọn nilati maa raeti ni igbagbogbo fun lilo gẹgẹ bi atẹgun iṣẹ igbelike ilẹ abinibi wọn, o si pari ọrọ rẹ pe, ki awọn ọmọ ẹgbẹ maṣe rẹhin ninu ija wọn fun igbeleke ilẹ abinibi wọn ati orilẹede Naijiria ni apapọ. O fi kun pe ki ẹgbẹ ti ọdọ yi maṣe fasẹhin nigbakugba ti awọn ẹgbẹ agba ba pe wọn fun iṣẹ aṣepo fun idagbasoke ilẹ baba wọn.

Baba Aladura jalaisi

Okiki kan kakiri Ifo ati agbegbe re nigbati nwon tufo iku Ọgbẹni Joseph Shonude Adeosun ti apele re nje Baba Aladura.

Ohun ti olubo ma jinnijinni ba awọn olubakedun ti o wa sibi ile ologbe na, ni igbati nwọn ba oku re ninu aṣọ ogbo funfun balai laiko jẹ pe enikeni lo fi di i, pe e ni gbogbo won tuka ni okiki ba tun gba adugbo lekeji, gbogbo won si beresi so kakiri pe "A ko ri iru eleyi ri o, ki oku ku tan ki a ba aso isinku lara re laiko jẹ pe awon ebi tabi omo re ni nwon fi bo o lara.

Ọgbẹni Adeoshun ku nigbati o di eni odun marundilogorun, o bi omo mejidilogun ati omo-omo mejilelogbon.

Ninu awon enia jankanjankan ti o wa sibi isinku Ologbe na ni awon Ogbeni Yusufu Ogidan ati Oluwole Adeosun Sule Adeosun, (Baba Taju) pelu Iyaafin Oluwemimo Olumuyiwa ati awon omo oku yoku.

Egbe Serafu pari ija

Ni ọjọ aiku ti iṣe ọjọ kejila oṣu kini ọdun yi ni ede koyede ti o wa larin Ọgbẹni Michael Olu ọtun pẹlu awọn Ijọ ti Kerubu ati Serafu Ileayọ wa si ipari patapata. Ki ija yi to wa si ipari, ejẹ nkan ti o la awọn opolopo enia lagun nipa pe ki nwon lo se iwe owo lati odo agbẹjoro fun aiko to suna iwa ti an ogbẹni na aba ti ko si dun mo awon opolopo enia ninu lara awon enia Ijo yi gan.

Sugbọn ni ọna ara, lọna bayi ni Ija na wa si ipari [illegible] ti awọ̣ lati owọ ipade [illegible] Ile-Ife ati agbegbe rẹ pẹlu Ilesha nse ni ojoojumọ ni abẹ Olusakoso Olusagutan Adesoji A. P. D. Ile-Ife.

Lẹhin ọrọ lati ẹnu Alagba kan Ọgbẹni George Odeniye, ni ọnikan na tun sọrọ loruko gbogbo awọn ọdọ — Ọgbẹni Kehinde Fatiregun ati ọlomiran lati ọdọ awọn obirin Iya wa Madam Victoria Ala sọrọ lori ede ko yede yi ti o si le ba nkan jẹ lọjọ iwaju ti a ko ba tete pa ina rẹ kiakia.

Laiko pe papọ ni Olọrun fun ra Re wa lo awọn enia wa lati Ile-Ife fun ipari rogbodiyan na ti ko tun ni sọrọ mọ lodai nipe pe ki ọmọde ma a bọwọ fun agba ati paapa pe ki awọn agba mo iyi awọn ọmọde ni kikan pe ẹni iyi won ni awon omode na jẹ. Ki Oluwa bawa da owo ija duro ninu Ile, Ijọ, Adugbo ati ni inu ile onikaluku. Ki owo fi wa jẹ ore ara wa. Amin.

Lawco Babson Oguns

Jaguda jale ni Ṣọọṣi

ỌRỌ bajẹ koja idaji, ha! si ṣe gbogbo awọn olubakẹdun ti o wa si ibi isin ikẹhin ni Ṣọọṣi St., Saviour Ijẹbu Ode ti nwọn ṣe fun Oloye J. O. Shonibarẹ ni ọjọ Aje ti iṣe ogunjọ oṣu kini ọdun yi nigbati ọmọjaguda fi ọbẹ afẹfẹ ge Oludari Ile iṣẹ African Press ni apo agbada ninu Ṣọọṣi.

Iṣẹlẹ buburu na ṣẹlẹ ninu "St. Saviour's Church" nigbati Ọgbẹni J. L. Oni agba "Odudo-iyọra oku" ti awọn ile iṣẹ iroyin African Press fi da ologbe na lọla lọ si [illegible] posi rẹ ni awọn ọmọjaguda ba fi ọbẹ afẹfẹ dabira si agbada rẹ sugbọn nwọn ko ri owo ja ni apo rẹ.

OLOYE AKINTEMI 'OBU'

Ejo tu ere bọlu ka

Ọrọ di ho lọ yago fun mi bale ko duro mọ sokoto lori papa isere bolu afowo gba ni Eko ni aipe yi nigbati ejo kan bo si arin ogba isere ẹgbẹ di awon elere "Syrian Club" lakoko ti ẹgbẹ elere 'Cosmos' ati Federal Guards' nse ere idije bolu afowogba lori papa na.

Bi awon elere ti ri ejo yi ni gbogbo won ba tuka pe e gbogbo won si beresi salu ara won bi ejo na si ti ri gbogbo enia ti nwon nsa sihin sohun, ni on na so ara re di "iran" ti o bere si gbe orun sihin sohun bi eniti o njo gangan ri on na si so ara re di okan ninu awon agbabolu.

Bi ogan ni awon elere bolu na he Igi pako ati oko tiwon si pa ejo na ki nwon to ma ba ere won lo, sugbon ki awon to pa ejo na o ti da erin ariotakiti pa opolopo ni akoko ti o njo gangan lori papa na.

Ni ipari ere idije na, awon egbe elere bolu "Cosmos" ni o gbeiye lowo awon egbe elere "Federal Guards" awon elere "Cosmons" di agbon marundinladota ru si awon "Federal Guards" awon na si sa ogun agbon pada.

Ayorunbo Pada

Irọkẹkẹ ala wọ igboro Ijẹbu—Ode, nigbati o de si etigbọ awọn enia ilu pe oku kan tun di alaye ni ile iakulaku Ijẹbu-Ode.

Agbajowo enia ni o jẹ fun awọn nọọsi ile iwosan Ijọba Ijẹbu-Ode nigbati Iyaafin Ayọka Muraino eni ogun ọdun, ti nwọn gbe oku rẹ wa si ile lakulaku ni ibi ile iwosan yi fun ayẹwo ohun ti o mu dakẹ lojiji tun pada di alaye lai gun ni abẹrẹ tabi ṣe iṣe iwosan kan si lara.

Koko bi agbọn ni ara Iyaafin Ayọka Muraino lẹ nigbati ọkọ rẹ Muraino Tijani fi ile rẹ ni adugbo Ilọwa Ijẹbu-Igbo lọ si ibi iṣẹ ni owurọ ọjọ ti iṣẹlẹ na ṣe.

Ọkunrin na sọ fun onirohin wa pe, nigbati on pada ti ibi iṣẹ de ni on ba ọna yara iyawo on ni titi gbọningbọin lati inu, o si fi kun un pe, ẹẹkẹẹ ni ẹru ti ba on nigbati on kan ilẹkun ibi, ti ọkan ko si dahun lati inu ile na wa.

O sọ siwaju si pe, on ko ni okan mọ, on ba ọna agọ ọlọpa lọ nigbati ọlọpa si de nwọn fi agbara si ilẹkun "si iyalenu mi mo ba iyawo mi bi oku ti nwọn ti sọ ni okuta pa."

Lẹsẹkanna ni nwọn ti gbe oku Ayọka lọ si ile lakulaku ni Ijẹbu-Ode fun ayẹwo, nigbọti ko pẹ lẹhin ti nwọn gbeda ibẹ, ni Ayọka bẹrẹ ngmi kikankikan ti o si nmira bakanna.

Lẹsẹkanna ni awọn ti da obinrin yi pada si ori ibusun ni ile iwosan fun itọju.

Aja pa asọde oru

Gbagi ni aja Ọludari ile Ise kan ni Dugbe Igbo Jos so asode oru kan lọwọ lẹ rẹ, o si bọjẹ yaarayaara.

Lẹsẹkẹsẹ ni awọn gbe lọ si ile iwosan Jos nibi ti o si ku si.

Enia mẹwa ni awọn ọlọpa mu ni Kano lọwọlọwọ lati ṣe iwadi ikọ ti o pa ọkan ninu kan ti awọn pe ni wiro.

Egbe Odo Afenifere Yan Oloye Egbe

Egbe odo Afenifere wọọdu 'F' Awoyokun yan awọn Oloye titun lẹhin titu awọn oloye ẹgbẹ wọọdu na ka laipẹ yi.

Irohin ko to afojuba ni ojo kẹkanla oṣukejila ọdun yi nigbati awọn ẹgbẹ yi nyan awọn Oloye wọn Awon ato po lo bi ona ayọ, awon obinrin lati oja kajola ti Ibominran gbogbo wa. Ati awon enia jankanjankan lo pese sibi eso yi, Ibosi Awo!Awo!Awo! lotun-losi koye fi enu so.

Aw n Oloye na ni:

Alaga Egbe Ogbeni N.A. Oyenile; Igbakeji Alaga Ogbeni G.O. Fatiregun; Akowe Igbekegbodo ogbeni T.A. Bewodi; Igbakeji akowe ogbeni S.O. Onifayo; Akowe owo ogbeni S.A. Adeleye Akapo owo ogbeni S.F. Shonaike; Akowe Igbekegbodo ogbeni P. O. Oshunuga; O'ubewo owo egbe ogbeni A. A. Oshinowo; Akowe onirohin ogbeni M. O. Kehinde; Olubewo iwe egbe ogbeni J. [illegible] egbe ogbeni G. O. Mustafa; Akowe Alabewukele ogbeni F. T. Bareewa; Oniria ajo egbe ogbeni Akanbi ati S. P. Onifayin; Latosesu egbe S. Ajala ati Alufa I. A. Ogundipe.

Baba fun ọmọ rẹ loyun

Ọwọ awọn ọlọpa ti tẹ ọkunrin agbẹ kan ni Akure ti o pa ọmọ rẹ obinrin nitori ifẹ.

Irohin ti o jade lati ile iṣẹ awọn ọlọpa fi ye ni kedere pe nwọn ti fi ọjọ mu Adesiyan Ige ti ojẹ baba ọmọ fi nwọn pa na gẹgẹ bi eniti o yinbọn pa ọmọ rẹ nitori ti ko sọ fun eniti o fun ni oyun.

Ariyanjiyan lori oyun inu ọmọbinrin na bẹrẹ ni abule Olorunda ti o jẹ iwọn ogun ibuso si Akure nigbati baba ọmọ na ṣe akiyesi pe ọmọbinrin on ti un mọ akoko ati bi ọmọ.

Sugbọn nigbati baba na bere lọwọ ọmọ rẹ eniti oni oyun, owi fun baba rẹ pe on ti sọ eniti o ni oyun fun iya on, ki ki baba on lọ bere lọwọ rẹ.

Sugbọn nwọn ko mọ ibiti iya ọmọ na lọ lati gbọ ọrọ lẹnu rẹ.

Nigbati awọn ọlọpa bere lọwọ baba ọmọ na, o sọ fun wọn pe on ni on pa ọmọ on Olurẹmi nitori pe o ti nṣọ kakiri pe on ni o fun un ni oyun.

Nwọn ti gbe oku ọmọ na lọ si ile iwosan 'Wesley Guild Ilesha' fun ayẹwo.

Rorẹ ati Awọ-ara ti ko dara yio san larin wakati mẹrinlelogun

NIXODERM Je oogun [illegible] [illegible]

[illegible] NIXODERM [illegible] NIXODERM [illegible] NIXODERM [illegible]

NIXODERM

ISINKU

Ojọ ala ni ojọ Aje ti ịṣe Ogunjọ Oṣu Kini ọdun yi ni ile Naijiria nigbati awon gbe oku Oloye Samuel Olatubọsun Shonibare Asiwaju Ijẹbu lati ebute ọkọ afarufu Ikẹja wa si Ijẹbu Ode fun eto Isinku re.

Ogunlogo awon enia jankanjankan l'okunrin ati l'obinrin ninu mọto ayokele won pelu asọ ofo lorun ni nwọn wọ ile oku Oloye na titi de ibi isinmi re ikẹhin.

Nigbati o di agogo meta osan ojọ na ni mọto ti oku Oloye na wa ninu re pelu ogoro mọto ayokele de abole kan Ijebu Ode ti nwon npe ni Agoro, lati ibe ni awon olubakẹdun ti to lọtun ati losi ni ibuso mefa titi de Ijebu Ode.

Awon mọto ayokele na pelu o k e almoye enia si berẹsi fa bi igbin wọ Ijebu Ode. Gba'a ti nwon wọ ilu ni awon olubakẹdun m i r a n ti nwon wa pade oku na ni ẹnu ibode berẹsi kigbe Awo! Awo!! bẹ ẹ ni awon ọde berẹsi yiabọn fun ti ayẹsi oku na olukaluku si berẹsi tẹ imọ ọpẹ s'oju titi, lori awon imọ ọpẹ na ni mọto ti o gbe oku Oloye Shonibare nyọ lọ gẹnnẹ titi o fi de ile re.

Nigbati o di agogo mẹ rin irọle ojọ na ni nwon gbe oku re wa si i l e Olorun Saint Saviour's Church Ita Olowojoda, Ijebu-Ode nibiti nwon gbe se isin ikẹhin fun.

Bisọbu S. O. Odutola ti Ibadan ni o ṣe isin ikẹhin na. Nigbati iwaasu re, o ni "Laiseanini, iku Oloye Samuel Olatubọsun Shonibare je adanu nlanla fun ile Naijiria nitoripe ni igba atye re, o segudg idagbasoke oge Naijir ti o ninira ni gbo wa O jẹ olufọk si aye r Sọyẹ Brea ni iso". Nigbati si ọ pe Sam un Shonib mẹrẹgo ọm ẹfẹgẹ ati do ni igba ni "ainu

Aworen oke yi ni igbati Ologbe Oloye Shonibare wa ninu ewu oye re pelu itagbe lejika ati awon ereru ti o yi ka l'ọtun ati l'osi

Pagidari igi da !

Aworan isale yi ni igbati ọgẹrẹ Ologbe Shonibare fi ọbẹ irọle bu erupẹ sori posi re ninu saare.

Aworen oke yi ni igbati awon ogunlogo enia duro iẹmi ọna Sọyi lati ṣe isin ikẹhin fun ologbe Shonibare

ỌLỌRUN KỌ OWỌ ELE (2)

SALLAM ALAEKUN fun gbogbo enyin olugbagbo ododo. Iwasu mi ọṣẹ yi duro lori 'ỌLỌRUN KỌ OWỌ-ELE' Gegebi Ọlọrun ti so fun ANABI wa MOHAMMED (P.B.O.H.) ninu Kurani mimo, Suratu Bakarat 2, Ayat 278. O ka bayi pe:- Enyin olugbagbo ododo, ẹ beru ỌLỌRUN, ẹ ju ele ori owo eyin sile bi enyin ba je onigbagbo.

Iwon iwa olugbagbo ododo, keyrel tile odia inu ayat yi. Olowa pe kaṣ nina ayat yi fun iwo ti o je olugbagbo lati fi ele ori owo yin sile fun awon elole, ki o si gba iye awon re pada nigbati awon bari. Eyi o dara ju ki o fi iya owo s'e nara fun wọn, ki o wa ma rati esan maje pe ni kekere o o le dina ona lodo ỌLỌRUN. Ara e

Lat owo Alhaji ABDULBAKI MOHAMMED, IWO.

na ti gbigbe sile kanaibo lowo enni o fun ni sile kan. Ti iwo ko le ti d a okan onikan pada fun, o ni gbese lorun niyen. Bi o si ti mo yen, maje pe ni kekere o o le dina ti o ku je. Bakanna lo ri je ele ti anpe ni Riba, je ni ona Ikoye bi owo gb. wonighwemi, ati owo ti a j. nibi eri eke ti o je. Owo ehin ti o ybo nibi ojo on ti o du, ati owo ti iwo abula onitubu tabi alhaji onitubaonisse okun gb ti o fi y a oko ati aya, tabi ti o fi s tura buroku yo enia kuro ni ilu, tabi iyokuro ni ipo giga kan tabi yiya si w re. Gbogbo ona ti a ka sile yi je ona ikoye. Iwoo ki o jo iwa kiakia, ki o ma ṣe ona da-nidaste ti ỌLỌRUN fe. Ranti pe bi o ba sun, iwo k o kun yara kan iwo ko si le je onje meji sina lekanna. Mese jeki onje so o di oloti buruku o. Sallam Alaekum

LAKUREGBE LO

Nigbana ni o wipe mo duro lowo

DeWitt's

Kidney & Bladder Pills

Nigbana, bi Irora re ti se lo, awon kuro ogbogi De Witt ni o mu o lokun, ati agbara nitori nwon tun aje re se dada. Ra koro ogbogi De Witt dia nitoriyi ki o ai ni Irora ati agbara re pada.

FUN ILERA ATI AGBARA

DeWitt's

KIDNEY & BLADDER PILLS

EGBOGI ATEJESE TI GBOGBO AIYE TI MO

AWORAN oke yi ni igbati nwon gbe oku Shonibare wọ Ijebu Ode, nibi mọto ti ami atọka wa lori re ni pesi ọ wa.

AWORAN isale yi ni yi awọn ogunlogo awọn enia pelu imo ope lowo wọn ati egungun ti nwon nyombo Awo! Awo! niwaju oku Shonibare de ile oku.

O di

Ha.' ojọ ala ṣẹ Na
Shonibare d'ologb
Okunrin lookoboj
Akunnuyẹjọ lo laida
Erẹlu wa loke An
Ile mi titi.
Ha! Shonibare
Ọmọ Obasi
Agbọrunjegun
Ṣe bẹ ẹ d'ani ibor

x x x

Jinnijinni nu
T'omọde tagba
N'ile Naijiria
Gbat'ero aporomag
Nke tantan ni ojọ
Ti i se ojọ ketac
gun osa kiri odun y
Shonibare je pe
Olorun ni 'a Lond
Awo lọ o
Ijọla b'ofẹ
Okunrin kẹ
Ab'ija kunkun yo be
Od'eni orun
Ha! ile ma
Nje enia o
B'ojo ko ti
Meni owọ
Bẹẹ ni iku
Ko m'eni A pa
Iba j'epe
Ojo m'eni
Owọ ni
T'iku si
M'eni a npe
Iku ki ba ti
Pa Shonibare
Opomulero ehin
Egbe Olọpẹ
Sunre o-Tobosun.

x x x x x x

Enyin egbe Olọpẹ
Jakejado agbaiye

U SHONIBARẸ PABAMBARI

o se gudugudu meje fun idagbasoke ati igbeleke ogo Naijiria tobẹ gẹ ẹ ti ominira kikun fi bọ si ọwọ wa l'oju ẹmi rẹ. O jẹ ounfọkansin ni igbesi aye rẹ, ọmọ Ijọ Sọosi Breadfruit l'Eko ni isisiyi".

Siwaju si i, Bisọbu na ṣọ pe Samuel Olatubọsun Shonibarẹ jẹ opomulero ọmọ ẹgbẹ Afẹnifere ati oselu olododo ni gba aiye rẹ. O ni "nisu nkan marun ti Olọrun ẹleda fi nta eda lorẹ, mẹrin ni Ologbe wa ni: okansoso ti o ku ti ko ni ni ẹmi gigun, sugbon sibẹsibẹ o se aiye rere ni iwonba igba ti o lo na.

Ni ipari iwasu rẹ, o ro ẹbi, orẹ ati awon ẹlẹgbẹ ologbe na pe ki nwon ma se banuje bi awon ti ko ni ireti, nitoripe o ti daju pe a o pade lẹsẹ Jesu lojọ Ajinde." O si tun bẹ awon ẹbi Oloye Sẹ onibarẹ pe ki nwon o ma radọ bo awon ọmọ ti ologbe na fi si aiye lọ ki nwon ma ba a mọ riri iku baba won.

Aworan egbẹ orue yi ni ti ologbe Shonibarẹ ngati oya foto pelu iyawo rẹ ati iyafin Oloye Awolowo ni kete ti o je oye asiwaju Igbobi-Ode tan. Iyafin Awolowo ni owa ni ọwọ orun dagbe ni.

Ọmọ Oduduwa ni wa

Enyi ọmọ Oduduwa
Mo ki nyin
N'ile l'oko
Ati enyin to wa lokere
Oro mi oni
O dori ko dori
O dori egbẹ Oduduwa
Oduduwa ni a mọ
Ni baba la
Ira.n Yoruba
Ti Olọfin ti je o?
Ib i oruko yi gba yọ
O jọ mi loju
O tun ya mi lẹnu
Emi ko si mọ
Boya Oduduwa ọ ko
Iran Yoruba ti ni
Emi ko mọ ọ
Bo ya inunibi u
Lo fẹ mu ki
Nwọn yi Oduduwa
Pade si O. fin ni
E je ki a bi agba lere
Awọn agba ni nwọn
Ma npa lowe pe
A ki bisu ori
Ki a fi ida de idodo
Ni ọjọ tow;n y'
Nwọn nwa ọna
Ati s ·ni iwaju
Di eso ẹhin
Edumare ko ni sọ
Ori di idi fun
Awa ọmọ Oduduwa Aṣẹ
Mo bẹ Oluwa aiye
Mo ton bẹ Edumare l'orun
Pe k'o fi oju anu wo
Ọmọ Oduduwa tak - taba
K' gbẹ yi toro jomi lọ
Eni ta sọ pe
Ki egbẹ Odud·wa tu
Oduduwa ni awon
Baba nla wa gba ni
Baba fun omo Yoruba
A oha ti se wa sọ
Akoko yi di ti Ọmọ Olọfin
Asa Yoruba dara
Iwa Yoruba wu ni j jọ
Awon wonyi n ayọ wa
Awon ni ẹwa ati ogo wa
Awon ni ogunbi wa pataki
E ma se jẹki ayapa
Si of n awon baba wa
E mase jẹki asako
Jinna si ọna iye
Kinla'a ko gbodẹ gbọpe
Omo Yoruba ko mo
Oduduwa ni baba wọnmọ
Ko wa je pe
Lto ti ajeji ni a tun nto
Eyi buru gidi
Tịsto ni ẹgbẹ Omo Odua
E ranti pe eni ba
So ile rẹ nu
So apo iya ko
Eni sọ oko nu
Ko apy ebi
E 'oju ile nyin
Nitori igb bin
Enyin atọkun ẹgbẹ
Mo ki nin o
E ku isẹ orilẹ ede yin
Edumare ko ni je ki
Wahala nyin dofo
E mase fi aye fun
Imo tara eni nikan
Lati da imọ nyin ru
Ise rere ni egbẹ Oduduwa nse

Lati ọwọ – Ade Ogundeyi

Ko ni ku, ko si ni run
Sugbọn o u re ni
Oduduwa yio ma gberu-si
Eniti o ba nwa ire ẹgbẹ yi
Ko ni ti, ko ni tẹ
Ko ni rago l'aiye
Ko ni lo akisa kẹhin nṣọ
A yoju rere Edu.are
Egbẹ Odua a toro
Ju omi owuro 'o
Enyin ọmọ karọ jire
E tẹti bẹlẹ ki ẹ gbọ
Inu mi dun
Mo yọ yọ yọ
Nigbati mo gbọ pe
Omọ Oduduwa ko gba
Gbere egbẹ Olọfin
Loto, o dara ki
Egbẹ Yoruba fi imo ṣokan
Sugbon ki se pe
Ki Odua di Olọfin
Gbogbo wa la mo pe
Ko si ohun ti o dun
Bi ireọ
Ko si ohun ti
O dara bi ifimọṣokan
A npete, a npero
Ko dabi ije
Ije ni pataki ju
Iwa ni akoja ero
Ise ni akoja ete
Oro tasan koye ẹmẹenia
Enyin Omọ Oduduwa
E mase jẹki
Ina ije nyin ku
Egbẹ Oduduwa yio
Ma gbile bi ọpẹ
Fun ire gbogbo Ọmọ Oduduwa
Enyin iran Yoruba
E o ngbohun na
Ko si ohun ti o yẹ
Enia bi ki o toju
Ogun ibi rẹ
Koda o tun bu egiri
Enyin ọmọ Yoru a
Ki ẹ ma gbọ
Egbẹ yi nikan
Ni ona iye si ayọ wa
E jẹki a jumọ siṣẹ pọ
Awon baba wa siṣẹ dewa
E jẹki awa na siṣẹ
Silẹ de omo wa
Ti wa ni Ibukun nla
Ti Eleda fi sori ile wa
Ile eleso yio hadi asa ẹbi
Ndao, ko ma ri
Sugbon oku ọwọ ire
Emi ati awon
Gegẹ bi awon kan ti nwi
Pe iya ajẹ omo Yoruba
Bo ba je bẹ
Kilo fa o?
Ijekoje wombia ati ile owo
Eleyi ni alebu Yoruba
E sun ikaka ki e rono jinl.
E je ki a sowọ pọ
Ki a toju ile wa
Nitori ọjọ igbẹhin
Bi igi ba gbarajọ
Nwon a di olu Igbo
Bi irawẹ ba gbarajọ
Nwon a dor.a odan
Enyin iran Yoruba e gbarajọ
Ki egbe orile ede yin ga
E su rigidi ke bo
Egbe omo Oduduwa
Fun ego ile Yoruba
Epo urogbo
Nibodi orogbo
Epo obi ni bodi obi
Epo atare nibodi atare
Enyin omo Yoruba
Eyago tun egbe Olọfin
Ki e si jarigidi bo
Egbe omo Odudwa
E mase gbo ti elegan
E ma feti si ti oniketa
Tisto ni egbẹ Omo Odua
E ranti pe eni ba
So ile rẹ nu
So apo iya ko
Eni sọ oko nu
Ko apy ebi
E 'oju ile nyin
Nitori igb bin
Enyin atọkun egbẹ
Mo ki nin o
E ku isẹ orilẹ ede yin
Edumare ko ni je ki
Wahala nyin dofo
E mase fi aye fun
Imo tara eni nikan
Lati da imọ nyin ru
Ise rere ni egbẹ Oduduwa nse

) digbose o, Shonibarẹ

! ọfọ nla e Naijiria
onibarẹ d'ologbe.
unrin kọsọbọto
uroyejo lẹladagbere
n wo Ide Amilala
mi tititi.
! Shonibaw
ọ Obanti
bọrunjangun
bẹ ẹ d'eri iboniran

x x x

aijiani ma
mode Lagba
lẹ Naijiria
at'ẹrọ asọmagbese
tantan si ọjọ eti
i se ọjọ ikadilo-
osu kini odun yi pe
nibarẹ je pe
run ni 'la Londonu
o lọ o
la b'ofọ
inrin jeje
ija kunkun se bẹẹ
ẹni orun
ilẹ ma
enia o
o ko ti
xi ọwọ
ni iku
m'ẹni Aspe
s'epe
m'ẹni
y ni
u si
ni a npa
ki ba ti
Shonibarẹ
mulero lọhin
ẹ Olọpẹ
fẹ o-Tubosun.
x x x x x
in egbẹ Olọpẹ
jado agbaye

Eku iroju
E ku aṣẹhinde
Shonibarẹ to lọ
S'orun a'akeji
Aremabọ
O digbere o
Od'ọdọ Oluwa
Telẹtẹlẹ ara,
Ati mọ pe
Iku ni igbẹhin
Olun gbogbo
x x x x x x x
Ha! iku wọle lojiji

Lati ọwọ J. O. Shoyinka

Iku f'ojika silẹ
Iku m'ẹni sere lọ
Samuel Olatunbọsun Shonibarẹ
Bi o ba
D'ajule orun
Ko k'awọn
Ajagun oselu
To b'ogun lọ
Masai ki
Sumbọ Jibowu
Ki Bọde Thomas
Balogun Oyọ atijọ
Pe ki nwọn
Ma sun asunpara o
Bẹẹni ko jisẹ
Fun Ṣegun Awolowọ
Bi nwọn ba nfi
Ara wọn l'orun lọhun
Pe gbọningbọnin
La duro lẹhin
Baba rẹ Awolọwọ
Pe b'oku irawọ
Kan l'oju orun
T'ẹgbẹ Olọpẹ
Ati ti Baba Nkẹnẹ
Lawa nṣe o
x x x x x x x
Ka pọ laiye titi
Bi "Metusela"

x x x x x x x
Enyin ẹbi Tubọsun
E s'okan giri
E ma si ṣe banuje
Bi awọn ti ko
Ni ireti.
Edumare Oba Olọla
Yio radọ bo yin
Yio t'oju ile at'ona yin
Yio si ṣe
Baba at'iya
Kalẹ fun nyin,
E ko ni r'ajalu
Bayi mọ
Od'ọjọ miran o
Samuel Olatubọsun Shonibarẹ
Ipade d'ọjọ Ajinde
Ka to rerin
O digbo rere
Ka to t'ẹfọn
Od'ọdan
S'ato r'iye
Bi Okin
Od'orun Alakeji

Aremabọ
Sun e o! Sunre o!!
SHONIBARẸ !!!

Awa Golu lọ si sare Laaye

Lẹnulọlọ yi ni awọn awa Golu meji ni Barakin Ladi ti o je Iwọn busọ mẹrin si ilu Jos ku si inu iho ile lẹhin ti ile ti se bo won mọle fun akoko diẹ lati ri aye mi.

Okan ninu awọn awa golu ti o wa ni ibi ti isẹlẹ yi ti se je osi-e egbẹ onise "Ex - Land (Nigeria) Limited"

Irohin fi han wa pe lojiji ni ona se awọn enia na mọ iho ile ti o si sin won laye. Nwon ko ti ri oku wẹn wa jade lati igbana di bi ati nrohin yi.

"Bakanna ni irohin kan lati ilu Dago ni agbegbe Jos kanna tun fi han wa pe ina nla kan bọ si agọ awon awa oje ni Dago ti o si sun ile mejidinlogbon patapata.

Classified Advert

10TH BOOK OF MOSES: Iwe kewa Mose. Iwe iranlọwọ nla fun awọn Egbe Aladura ijọba iwosan, ifihan, asọtẹlẹ. Asiri imularada lona ori iriji, asiri iso agan di olọmọ, igba ni lowọ awọn aghalagba. Agbọjọ, ki a si bere ki o si ri bẹẹ lonakona, mayehun atata. Poun kan (£1) pere. A le ri i ra lodọ MANAGER, 15, Araoti Street, Yaba, Nigeria abi ni ọwọ Abadu Akangbe, Ile Anabanlu, Ikire, via, Ibadan, ati ni ọdọ DAVID T. IWO, 19, AIEGUN.E STREET, ILUPEJU, MUSHIN.

FUN TITA

IWE ITUMỌ ALA lati ọwọ Josefu Alala o o Ajade ninu Iwe Itobi Yoruba lọọọọọ ni jade fun tita nisisiyi. O kan fun Ogun Ajebutan pelu Ja pere Postage 1s. SHOYINKA N2/99 Shitta Street, Ibadan.

Ran awon eree lowo Da ehin didun duro

MASE jẹki ifo-ilẹm, sisun d'di ona ofun ti ikolu iko ottutu tabi ti o-fee fi ojo kan ba orun tabi agbara lera re je laiko dan Mendaco wo egbogi elaala yi ki ise efin, abere-gigun tabi Ofon, sugbon nitoo eje ni o nsise, bayi ni o ti se de inu ndoforo ati awon iho-ona-ofun. Akoko re yiko bere si ran ara lowo lesekese ni ona meta. Ekini yio se iranlowo ati de kolobe kiki ti o ofu o lorun yio si yo o kuro: Ekeji lkeyi ko yio si fun o si anfani mimi kankn atipelu irorun orun asunwon. Eketa O nse iranlowo dide-iko mimi tipetipa ati sisun. A se ileri itorun nipa lilo re tabi ki o gba owo re pada.

RA ***Mendaco***

lowo apogun loni.

Awọn Ọmọ Yoruba ha wa ni ipo ẹhin bi?

ỌLỌLA Adetokunbọ Ademọla ati Dokita Moses Majẹkodunmi pẹlu awọn amugbalẹgbẹ wọn ti nwọn sọ pe awọn nja fun isọkan Yoruba ti npolongo lati osu kejọ ọdun to koja.

Nipa orişirişi ọna ti nwọn gba, nwọn ti fi ẹgbọn alumọkọroyin ko awọn bi melo kan jọ labẹ Ọba Alaiyeluwa Ọni Ifẹ ti nwọn si gbe aşẹ jade bi Ọba Kesari pe lati isisiyi lọ Ẹgbẹ Ọmọ Oduduwa ati Ẹgbẹ Abiku ti koi ti yọju sode ti nwọn npe ni Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba gbọdọ papọ gẹgẹbi ẹgbẹ ibilẹ kan ti nwọn yio si ma pe oruko rẹ ni Ẹgbẹ Ọmọ Ọlọfin.

Lati osu kejọ ọdun to koja ti awọn enia kan ti sọrọ ni gbangba nipa dida Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba silẹ, ogunlọgọ awọn enia iba şe Yoruba tabi iran miran lo ti sọ ọrọ tabi kọ orişirişi ọrọ lọtun losi lori ẹgbẹ titun na.

Ninu ero ti emi, awọn ọmọ Yoruba ti nwọn ti a riyanjiyan lori ọrọ ẹgbẹ na, yala ki nwọn faramọ ni o tabi ki nwọn lodi si ni nwọn ti şe bẹ ẹ ni ọna aitọ. işẹbẹ ati laakaye ti ko pe ye perepere nigbati awọn ti ki işe ọmọ Yoruba ti şe ariyanjiyan ninu aimọkan.

Ero mi ni lati jiroro mi ka ori ẹtanu lati işẹbe ati aimọkan nwọn alariyanjiyan wọnyi. Ninu gbogbo ohun ti mo fẹ sọ, - tito ati laakaye ni yio jẹ atọna mi.

Ọlọla Adetokunbọ ati Majẹkodunmi pẹlu awọn ẹrẹ wọn ti sọ pe nwọn ti sọ ọmọ Yoruba di ero ẹhin ni akejẹdo orilẹ-ede Naijiria ati pe eleyi le ti bẹ ọmọ Yoruba ko si ni isokan gegebi ti wọn Hausa pẹlu Ibo.

Idi ete egbe Ọmọ Yoruba ni pe lati mu awọn ọmọ yoruba siwaju ganan pẹlu awọn apakan ẹya miran, Ete yi ni awọn ọmọ Yoruba wa nse ariyanjiyan pe nwọn le ti bi ọmọ Yoruba ba wa si ipapọ ki nwọn sọrọ pẹlu ohun kanna."

Opọlọpọ awọn ọmọ Yoruba ni o ti sata ete Ẹgbẹ Ọmọ Yoruba yi gidigidi. Awọn ibere melo kan ti yio koko wa si ọkan ẹniti nwa otitọ lori ọro yi ni lati bere pe: Njẹ otitọ ati iwa ododo ni lati sọ pe nwọn nsọ awọn ọmọ Yoruba di ero ẹhin ninu igbokegbodo orilẹ-ede yi?

Ki ngto bẹrẹ sisọ ọrọ pato ti yio fihan pato boya bẹni tabi bẹkọ, mo fẹ ki a sọ Itumọ tabi asoye ohun ti nwọn ro nipa "igbokegbodo Naijiria."

Lajudaju, were alasọ ko gbọdọ sọ pe nwọn nsọ awọn Yoruba di ero ẹhin ni Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiri ayafi fun osu meje gbako ninu ọdun 1962 nigbati Balewa jọbẹ lori awọn Yoruba lọna apapando-do.

Nigbana na papa, eni ọwọ ọtun Ọlọla Ademọla Adetokunbọ ninu egbe Ọmọ Yoruba ti işe Dokita Moses Majẹkodunmi ni nwọn lo ni akoko na gege bi ohun elo fun Ijọba adanikanse, ifiyajẹni ati iaunibini si awọn asiwaju ọmọ Yoruba.

Mo ro pe ko si ẹniti o rahun pe nwọn nsọ awọn ọmọ Yoruba di ero ẹhin ninu igbokegbodo Ipinlẹ Ila-Orun, Ipinlẹ Ariwa ati Ipinlẹ agbedemeji iha Iwọ-Orun Naijiria.

Yatọ si awọn Ipinlẹ mẹta ti mo fi enu ba wọnyi, ohan kedere pe awọn ibomiran ti li sọ pe awọn ọmọ Yoruba ndi ero ẹhin ninu igbokegbodo tabi akoso Ijọba Apapọ

OLOLA ADETOKUNBO 'Olọọ-Agutan' Yoruba Kini

Naijiria ati ti akoso agbegbe Eko.

Akoso Ijọba pin si ẹka mẹta: Ile Igbimọ Asofin, Igbimọ Alabẹsekele Ijọba ati ẹka eto idajọ. A gbọdọ se ayẹwo awọn ẹka mẹtẹta yi finnifinni, ki asi mọ ori osunwọn ti awọn ọmọ Yoruba wa ninu wọn ki a to le fi ọwọ sọya se ipinnu lori ọrọ yi.

Ile Igbimọ Asofin: Ninu ile igbimọ Asofin Apapo Naijiria, aye ijoko ti o tọ si awọn omo Yoruba ko din si eyiti ofin pin fun wọn gegebi iye awọn enia ti o ngbe ipinlẹ wọn. Ohun ti o sele si awọn omo Yoruba wonyi ni o sele si awọn ọmọ Ibo ati Hausa.

Iyatọ pataki kan ni o wa ninu eyi: iyatọ na si ni pe nigbati awọn ọmọ Yoruba ti o wi ninu Ile Igbimọ Asofin Apapọ pin si yeleyele si inu ẹgbẹ Alakukọ, Egbe Afẹnifẹre, Egbe Olomi (NPC) ati Ẹgbẹ UPP fun idi ti ko saieji si ẹnikeni ni igboro, awọn Ibo gbaradi faramọ Ẹgbẹ Alakukọ nigbati awọn Hausa gbaradi faramọ Ẹgbẹ Olomi (NPC).

Bi awon Ibo ninu Ile Igbimo Asofin Apapo "ba soro pelu ohun kan" ki ise wipe nwon je omo Egbe Ibile Ibo ti nwon npe ni "Ibo State Union" tabi bi awon Hausa ba fi ohun kan soro be ki ise wipe nitoripe nwon je omo Egbe Ibile Jamiyyar Mutanen Arewa, yato si eyi, idi re ti nwon

Lati ọwọ Ọmọ Oduduwa

fi le fi ohun sokan sọrọ ni pe ogunlogo awọn enia ti o wa ninu ẹya mẹjeji na ni o wa ninu ẹgbẹ Iselu ti o wa ni ẹya ti wọn.

Nitoto Hausa kan ti işe ọmọ ẹgbẹ Olomi (NPC) ni alaga Ile

D—ITA MAJEKODNUMI 'O ọ-Agutan' Yoruba Keji

Igbimọ Asofin Apapọ nigbati Ibo kan ti işe ọmọ ẹgbẹ Alakukọ jẹ igbakeji rẹ. Bakanna ni ọmọ ẹgbẹ Alakukọ kan jẹ Alaga Ile Igbimọ Awon Alagba ni Eko ti ọmọ ẹgbẹ Olomi kan ti işe Yoruba jẹ igbakeji rẹ. Alaye yi yio ha fihan yekeyeke pe ẹgbẹ ti awọn enia wonyi nse lo gbe wọn de ipo ti wọn wa ki işe ẹya abinibi wọn. Bi ki iba se beni awọn ọmọ Ibilẹ Oke-Ọya meji ni ba wa ni ipo meji ninu ipo merin pataki wọnyi dipo ẹyọkan ti o bo si ipin ti won.

Şugbon nigbati o jẹ wipe ajumọşe Ijọba ẹgbẹ Olomi ati Alakuko ni Ijọba Apapo jẹ, awon eg e mej ji na gbodo pin oye mererin na dogbandogba gẹgẹbi adehun won.

Awon enia kan ti jiyan wipe bi o ba jẹ wipe ẹgbẹ Afẹnifere ti fi eti si ikede ogbon." ti nwon si ti darapo se Ijoba Apapo (mo ro pe nipa bi bebe fun ni nigbati Balewa ko pe ẹgbẹ na sinu Ijoba,) nwon iba ti pin awon ipo na ni ona ti o yato. Eyi ni oro boya. Bi o ti wu ki o ri awon ti o gbe ariyanjiyan yi sita gbodo mo dajudaju pe awon ti kolu laakaye ati iwa rere si omonikeji.

Ni ona kini, ko ba ogbon ati laakaye mu lati ro pe egbe Afenifere ti işe egbe tegbe togba kakiri orile-ede yi lati wa se işe ti ẹgbẹ ibilẹ Yoruba gbodo se nipa jija fun Yoruba nikan lai ka ifẹ ati ete awon omo orile-ede yi miran kun.

Ni ona keji ẹwẹ, bi a ba fi iye awon enia ti o wa ninu eya Yoruba si ori osunwon ipo kan pataki ninu ipo merin pataki fun gbogbo Naijiria se dede to fun Yoruba. Nipa eyi enikeni ti o ba jiyan pe awon Ibo koja aiye won nipa kiko aye meji ninu aye merin, nkan nfi ori ara re sanpon isele lasan ni, ti o si nfe fi egbe ibile ropo egbe işelu.

Igbimo Ijoba Ibile igboro Eko ni o duro gegebi Ile Igbimo Asofin fun agbegbe Eko. Awon omo Yoruba ni o poju ninu akoso Igbimo na. A ko le sai so nihin pe awon omo Yoruba ni o wa ni awon ipo ti o ga julo ninu Igbimo Ijoba Ibilẹ na.

Otito ni pe Alakoso eto arin ilu Eko ti ecku ida igbimo na wa lowo re je omo Oke-Ọya. Bi o tilẹ je wipe eyi koro lati gbo, ko le sai ribẹ ninu eto işelu.

Igbimo Alabesekele Ijoba, awon omo Yoruba marun ni o je Alakoso pelu ipin ise pataki ninu Igbimo awon Alakoso Ijoba Apapo: Awon ni: (1) Dokita Moses Majekodunmi (2) Dokita T. O. Elias; (3) Ogbeni T. O. S. Benson; (4) Oloye J. M. Johnson; (5) Oloye Olu Akinfosile; Marun ni awon omo Ibo ti o je Alakoso Ijoba bakana sugbon meta pere ninu won ni o ni ipin ise. Awon meta ti o ni ipin ise na ni: (1) Dokita Jaja Wachuku; (2) Raymond Njoku ati (3) Aja Nwachuku. Awon ti ko ni ipin ise ni: (1) Dokita K. O. Mbadiwe ati Ogbeni Nbazulike Amechi. Pun oye awon alaimokan, o ye ki nioka si pe Dokita Esin ati Ogbeni Mba ki ise omo Ibo gegebi Oloye Okotie-Eboh

ati Oloye Omo Osagie, ki ise omo Yoruba bi o tile je wipe Ipinle kanna ni omo Yoruba.

Emi ko ni lo lati ka awon omo Oke-Oya ti o wa ninu Igbimo Alakoso Ijoba Apapo. Sugbon bi enikeni ba fe mo iye won mo ro wipe mejila ni won, ara won ni Ototo Ijoba Apapo; yato si awon Alakoso merinla ti o je omo Isile iha Gusu Naijiria. Mo ro pe eyi je ino rere lopolopo lati Ipinle kan wa ti o ro wipe orun ni Eleda ti fun won ni ase wa lati ko idaji ohunkohun ti o ba je ti Orile-ede Naijiria.

Pelu gbogbo otito wonyi, o ha tan le je ero Olola Adetokunbo Ademola ati awon amugbalegbe re pe awon omo Yoruba di ero ehin ninu Igbimo awon Alakoso ti o je omo Yoruba ko ju ti awon Ibo lo tabi ki won ni iye kanna pelu won Hausa.

Awon ti ariyanjiyan yi ba gbun ni ara ti nwon si fe ni apa ninu ariyanjiyan na gbodo jeki a jijo fagagbaga leri re pelu okodoro oro.

Bi egbe Omo Yoruba ba fe se ototo pelu ara won ti nwon si fe gbe pinpin ipo awon Alakoso le ori nwon ti wa tele pelu awon osuwon eya ati iye eya kokan a gbodo gba wipe awon Ibo ni o ni eto lati rahun, ki ise awon omo Yoruba.

Okodoro otito ti o wa ninu eyi ni pe bi o ti wu ki o ri gbogbo awon Alakoso ti o wa ninu Ijoba Apapo wa ni ipo na nitoripe nwon wa ninu awon egbe oselu kan ni, ki si se nitoripe nwon je Yoruba Ibo tabi Hausa tabi ya miran.

Bi o ti wu ki o ri sa, gbogbo wa gbodo fara mo, papa awon asiwaju egbe omo Yoruba pe a fi were nikan ni o le so pe ipo ehin ni awon omo Yoruba wa ninu Igbimo awon Alakoso.

Ngko ri mo irahun ti nlo lowo bayi larin omo Yoruba ti nbe ninu ise Ijoba Apapo. Sugbon irahun na ha je ti awon omo Yoruba nikan bi nitoripe awon Ibo papa nrahun bakanna? Ohun ti awon nrahun le ninu ise Ijoba Apapo ni pe ne aiekara ko jamo nkankan mo lati de ipo giga. Bi o ba ri be ebi tani?

Ninu Igbimo Agbenisise Ijoba Apapo, Olola Samuel Manuwa je asoju ti o girikı fun iran Yoruba. O ha je wi pe Olola Manuwa ko ni okun to Ogbeni Majekwu ti o je asoju fun iran Ibo tabi Ogbeni Sule Katagun ti o je asoju fun iran Hausa?

Ojo ibanuje ti wole de bayi fun orile-ede Naijiria. Egbe Olomi ti ise akoso Ijoba Apapo ti ro wipe awon omo Oke-Oya nikan ni o gbodo je Alfa ati Omega ninu ise Ijoba Apapo.

Eyi ganani o wa fa rederede ti o wa ninu ise Ijoba Apapo nisisiyi, ti o si ba omi tutu si okan awon omo Yoruba ati Ibo ti o jinna hannahauun ninu eko won.

Bayi, o ye ki a se akiyesi pe awon omo Yoruba ni o se akoso awon ipo giga ninu ise segun Oyinbo, Ise ero, ise ofin ati bebe lo ninu ise Ijoba Apapo.

Eto idajo: Ninu ise eto idajo Ijoba Apapo Naijiria ati ni agbegbe Eko, yato si awon Oyinbo bi melo kan ati omo Ibo kan, kiki awon omo Yoruba ni o ni ise eto idajo.

Bi o ba je wipe awon gbodo pin aye ijoko awon adajo ti o wa ninu Ile-ejo ti o gaju lo ni orile-ede yi lori osuwon eya kokan gba wipe awon Hausa ni iba ni awon adajo ti o poju lo, ti awon Ibo iba si tele won. Sugbon mo ro wipe ise owo awon omo Yoruba ti o je adajo ni o gbe won de aye ti nwon wa, ki si ise tori eya won.

Bi o ti wu ki o ri, Olola Adetokunbo ko le rahun pe ipo ehin ni awon omo Yoruba wa ninu eto idajo Apapo Naijiria ti o wa labe Akoso re.

Bi awon ile ejo Ijoba Apapo se wa ni ikawo awon omo Yoruba, ti o si je wipe awon ni o poju ninu ise na, ni won se kun ibi ise eto ofin denu hamuhamo.

O ye ki nran awon egunnagbongbo egbe omo Yoruba leti pe nigbati ko si omo Ibo tabi Hausa ki o je adajo ninu awon ile-ejo giga Ipinle Iwo-Orun, awon omo Yoruba meji ni o je adajo ninu awon ile-ejo giga Ipinle Ila-Orun.

AWON AJO ISE IJOBA APAPO: Ninu awon Ile-eko nla Unifasiti Ibadan ati Eko pelu awon ile-iwosan won, yi o je ero amogo fun enikeni lati da aba pe ipo ehin ni awon omo Yoruba wa. Laise aniani, awon omo Yoruba kun ibe denu; nwon si nse ise won ni aiekara. Nwon wa nibe nitoripe ise owo won finna lanmahanna, ki si ise nitoripe nwon je omo Yoruba.

Ninu awon Ajo ise Ijoba iran Yoruba ni (1) Olola Kofo Abayomi; (2) Oloye Kolawole Balogun Alaga egbe oko oju omi; (3) Oloye Adewale Fashanu ti o ropo H. O. Davies (ibi ise Iwe Nigerian National Press); (4) Ogbeni Adeniran Ogunsanya (Igbimo aya-ni-lowo Ijoba Apapo); awon omo Ibo ti o je afiwe won ni (1) Oloye Dafe (Nigerian Airways), (2) Olola Odumegu Ojukwu ati (3) Dokita O. Ikejiani ti o wa nibi ise oko reluwe ati ibomiran. Awon Hausa ni o di ibi ise ina mona-mona ati ibi ise Ebute mu.

Emi ko so pe gbogbo re ni mo ti fi enu ba patapata. Jeki awon asiwaju egbe Omo Yoruba so ibiti awon eya miran ba gbe tayo iran Yoruba sita fun gbogbo aiye lati gbo.

Gege bi mo ti so tele, ki ise eya ti enia ba je ni o gbe awon enia wonyi de ipo ti won wa bikose egbe ti oko kan fara mo.

Bi o ti wu ki o ri, Olola Adetokunbo ti o je ogbonkangi Amofin, ti o si faramo ise ofin re ju ti iselulo ko ni sai faramo pe bokuso ti ko gbongbo rara ni fun enikeni lati so pe ipo ehin ni awon Omo Yoruba wa.

Ni ose ti o mbo, ma se alaira Irohin Yoruba fun idi ti Igbimo Olulaja Ademola lori ija Egbe Afenifere fi kuna.

Adebọla yọnda ipo rẹ

ALHAJI H. P. Adebọla babasale ẹgbẹ "United Labour Congress" ti yọọnu ipo re gẹgẹbi okan ninu ọmọ ẹgbẹ na. Bakanna ni o si ti fun kuro ni ọmọ ẹgbẹ "National Man-Power Board" ati ọmọ ẹgbẹ "Federal Labour Advisory Council".

Lẹnu lolo yi nigbati irohin na jade ni Eko, ogbeni Olu Johnson akowe ẹgbẹ ULC fi ye onirohin wa pe lati ojo kẹtala osu kini ọdun yi ni o fi jogo awọn ipo wọnyi.

ỌJỌ ỌJA ILẸ YORUBA

ILU OJO 'RU JAN. 29 (WEDNESDAY)

Eko Ati Agbegbe Re	Agege Ikeja Ebute Ero Ikorodu
Abeokuta	Lafenwa, Oba- Obada, Kajola, Ajegunle,
Ibadan	——— —— ——
Ijebu	Ikenne, Okun-owa Erunwon Omu, Mamu,
Ijesha	Ibefu Atikori Imushin Ago-woye Ijesha
Ondo Ati Eti Odo	Esa-Oke Ijebu–Ijesha Ilase Epe Iloba Iperindo Imuroko
Egbado	——— — — —
Ogbomosho	Oko ——— - -
Ekiti	Oke mesi Ifaki Igede Ikole
BINI	Uromi
Eti Odo	——— —— —
Igbajo	——— — -

ILU OJO 'RU JAN. 30 1964 (THURSDAY

Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo ——— ———
Abeokuta	Atan Agbado Ifo Itori Itoku Isabo Odeda
Ibadan	Olode
Ijebu	Aiyepe Sagamu Ita osu Ogere Irolu Itele
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilara.
Egbado	Alagba, Ilaro
Ogbomosho	——— ——
Ekiti	Ilogbo Ishan
BINI	Eke
Eti Odo	——— ——
Igbajo	

I L U OJO 'BO JAN. 31 (FRIDAY)

Eko Ati Agbegbe Re	Obun-Eko.
Abeokuta	Ijoko, Iberekodo, Asu, Wasimi, Araro-
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda,
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishan
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo
Ondo Ati Eti Odo	——— ——
Egbado	——— ——
Ogbomosho	——— ——
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	——— ——
Eti Odo	Kokori ———
Igbajo	——— ——

I L U OJO ETI FEB. 1 (SATURDAY)

Eko Ati Agbegbe Re	Mushin Badagry
Abeokuta	Otta, Abalabi, Sodeke, Omida, Ilawo.
Ibadan	——— ——
Ijebu	——— ——
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Iloko
Ondo Ati Eti Odo	
Egbado	
Ogbomosho	Araromi ———
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	——— ——
Eti Odo	——— —
Igbajo	Iloro ———

ILU OJO ABAMETA FEB. 2 (SUNDAY)

ko Ati Agbegbe Re	Agege, Ikeja Ikosi, (Epe).
Abeokuta	Lafenwa Obada Oba Kajola Ajegunle
Ibadan	——— —— ——
Ijebu	Ikenne Okun-Owa Erunwon Omu Mamu Ibefun, Atikori, Imushin, Ago-Iwoye, Ijesha-Ijebu. Isara Imodi
Ijesha	Esa-oke, Ilase, Epe, Iloba, Iperindo, Imuroko, Ikeji.
Ond'o Ati Eti Odo	Igbo-Egunre
Egbado	——— ——
Ogbomosho	Oko ———
Ekiti	Oke mesi; Ifaki; Igede; Ikole
BINI	Uromi
Eti Odo	——— ——
Igbajo	———

I L U OJO AIKU FEB. 3 (MONDAY)

Eko Ati Agbegbe Re	Oyingbo,
Abeokuta	Atan, Agbado, Ifo, Itori, Itoku, Isabo,
Ibadan	Olode
Ijebu	Aiyepe, Sagamu, Ita-osu, Ogere, Itele, Ita, Iloti
Ijesha	Ibodi Ibode Kajola
Ondo Ati Eti Odo	Oka, Ilora.
Egbado	Alagba Ilaro ———
Ogbomosho	——— ——
Ekiti	Ilogbo, Ishan.
BINI	Eke
Eti Odo	Kpaksang, Bomadi, Ekeremor, Tonigbene
Igbajo	——— ——

I L U OJO AJE FEB. 4 (TUESDAY)

Eko Ati Agbegbe Re	Obun Eko ———
Abeokuta	Ijoko Iberekodo Asu Wasimi –
Ibadan	Ijaiye-orile, Fedegbo, Oyedeji, Egbeda
Ijebu	Ilishan Odogbolu Atan Imope Ishatı Isara
Ijesha	Iwara, Ejioro, Odo, Ibokun, Esa-Odo,
Ondo Ati Eti Odo	——— ——
Egbado	——— ——
Ogbomosho	——— ——
Ekiti	Egosi, Odo-Aiyedun.
BINI	——— ——
Eti Odo	Kokori
Igbajo	——— ——

I L U OJO ISEGUN FEB. 5 (WEDNESDA

Eko Ati Agbegbe Re	Mushin, Badagry
Abeokuta	Otta Abalabi Sodeke Omida Ilawo –
Ibadan	——— ——
Ijebu	——— ——
Ijesha	Oshu Itagun Odogbo Idoko Ilo
Ondo Ati Eti Odo	——— ——
Egbado	——— ——
Ogbomosho	Araromi ———
Ekiti	Oke Aiyedun
BINI	——— ——
Eti Odo	——— ——
Igbajo	Iloro ———

Alọ o Alọ

1 Ọmọ buburu ṣokun wọgbe o.

2 Oku ati ọdun mọ' dun, oku ati osu mo'ṣu nwọn ge ni ekan o nṣeṣọ o

3 Nwọn ni ki ngbe wa mo gbe wa, nwọn ni ki ngbe pada wa mi o le gbe pada o.

4 Oku ati ọdun mọ' dun, oku ati osu mo'ṣu awọn marun ngbe ti, ọde odi, o ni ki nwọn gbe ohun ṣokale pe on le rin o.

5 Awẹ obi kan aje de Oyọ

6 Aṣọ baba mi kan lailai, aṣọ baba mi kan lailai, igbati orun ba ran ni wọn ka, ti ojo baro ni nwọn nsa o.

7 Okuta peregede ko se sa olubọ si o.

8 A ngunyan aja njo o.

9 Akuro kotokoto nwu irun dudu gaun- n.

10 Otogun Ṣokoto, gun oko.

11 Ilo ni chin, ko ni erigi, on rorin ihombo o.

12 Orisa baba mi kan lailai, orisa bapa mi kan lailai ojo-jumọ ni nwọn nkunle bọ o.

13 Akukọ baba mi kan lailai, akukọ baba mi kan lailai, owo ni onje, ki je agbado.

14 Ọmọ dudu goke, ọmọ pupa nfi owọ ra idi rẹ o.

15 Mo sun isu gborọ mi ole je tan o.

Awọn ọdọ Igbajọ parapọ

Irohin ko to afojuba ni opopo Inalende, nigbati awon ọdọmọkunrin Igbajo da Egbe Akọni ọdọ Igbajo sile (Igbajo Dynamic Youth Association) ni ipari ọse ti o koja yi.

Eniti o koko soro nibi ipade alarinrin na ni Ogbeni J. Ayo Famoile on ni o sọ idi pataki dida egbe na sile. O ni bi o tile jepe egbe yi kii se egbe oselu, oto akoko lati ri pe a wa isokan larin awon asiwaju wa lokunrin ati lobinrin nipa ifọwọsowọpọ.

O si sọ bayi pe Egbe Odo yi yio ja fun idagbasoke ati ilosiwaju ilu lati rii pe ọna Igbajo si Imesi Ile le seşe laipe ọjo.

Osi tun fenu ba awon ifa-ẹhin ti Igbajo ni nipa ọrọ oselu. Osi fi siw ju pe, eyi je ohun ti awa ọdọ ni lati le fi mọ pe egbe oselu kan kole se iu lanfani ti nwon ko ba ni asiwaju ti gbogbo aiye feran.

O sapejuwe opo awon oselu wa oni gegebi anikanjọpọn, ti won mọ ti ara won nikan.

Enikeji ti o soro ni Ogbeni Oyeniyi Ojo, o kan sara si awon asiwaju nla ti o mu ki a ti ni ile ẹko giga Kiriji fi hqsii. Osi tun wa ke dun pe akoko to lati fi egbe oselu pamọ lati le jiroro ilosiwaju ilu na eyiti gbogbo aiye le fi mọ ilu 'gbajo.

Ogbeni Ojo so siwaju sii pe aiti ise po ni ilu, kini a fi'din eyi ku? A fi bi egbe odo Akọni gbaradi lati da oju ko isoro ti o fa aisi ise eyiti koko re je aini vranlọwọ ati ifọwọsowọpọ awon enia wa.

Eyiti o kan awa papa gege bi egbe lati se Ighin ti egbe wa ba ti fi idi mule dada ni lati da ise sile ni ilu Igbajo, eyiti awon omo wa yio fi ri ise se.

Ipade na si fi ase si iwe ti Ogbeni Ojo ko si Dokita Samuel Aluko, oluko Agbani nibi Eko isunna owo ni ile Eko giga Unifasiti Ife lati wa jiroro bi awon ohun ti awon dawole yio ti se le ese.

Dokita Aluko yio si ba egbe na soro bi ati le fi ese egbe mule, ati bi egbe se le ri owo se itoju Egbe.

Dokita Aluko yio so oro yi ni ile ikawe America ti o wa ni Mokola.

Ni ipari awon omo egbe si yan awon Oloye ara awon Oloye egbe na ni Ogbeni J. Ayo Famoile, Alaga, Ogbeni Ayo Oniti Akowe Owo, awon Ogbeni Adegbite Akerele ati Ogbeni Bode Taylor Akowe egbe

Egbe na yio ni eka ni gbo gbo ilu bi Eko, Oshogbo, Igbajo Ilesha, Ife Akure, Ilorin ati awon Ilu miinla miran jakejado orile ede Naijiria.

Ni ipari awon fi ojo ipade miran si ojo Aje ti ise ojo ketadinlogbon osu kini odun yi awon yio si bere ipade na ni dede agogo mefa irole.

Asobade ere bolu

DIVISION I

Aston Villa v West Ham	1(x)
Bolton v Nottingham For	2
Burnley v West Boro	2
Fulham v Leicester	x(2)
Ipswich v Birmingham	x
Liverpool v Sheffield U	1
Manchester U Arsenal	1
Sheffield Wed. v Everton	1
Stoke v Blackburn	2
Tottenham v Chelsea	1
Wolves v Blackpool	1

DIVISION II

Charlton v Derby	1
Grimsby v Huddersfield	x
Leeds v Cardiff	1
Leyton v Middlesbrough	1(x)
Oouthampton v Manchester	2
Plymouth v Bury	x(2)
Portsmouth v Scunthorpe	1
Preston z Newcastle	1
Rotherham v Norwich	1
Sunderland v Swindon	1

DIVISON III

Bournemouth v Barnsley	1
Bristol R v Watford	x
Coventry v Hull	1
Grewe v Port Vale	1
Crystal Palace v Bristol C.	1
Luton v Mansfield	x(2)
Notts Co. v Peterbrough	2
Oldham v Southend	1
Q.P.R. v Colchester	2
Reading v Brentford	1
Walrall v Shrewsbury	x(2)
Wrexham v Millwall	x(2)

DIVISION IV

Bradford v Chester	x(2)
Chesterfield v Brighton	2
Darlington v Exeter	2
Halifax v Bredford City	2(x)
Hartlepools v Southport	2
Oxford v Carlisle	2
Stockport v York	1
Torquay v Aldershot	x
Workington v Rochdale	1

SCOTTISH DIVISION I

Airdrie v Dundee U.	2
Dundee v Q. of South	1
Dunfermline v Celtic	x(1)
Falkirk v Rangers	2
Hibernian v Motherwell	x
Partic v Kilmarnock	2
St. Johnstone v Aearts	2
St. Mirren v East Stialing	1
Third ostnark v Aberdeen	2(c)

SCOTTISH DIVISION II

Alba v Stirling	2
Arbroath v Albion	1
Ayr v Raith	x
Clyde v Brechin	1
Dumbarton v Stenhousemuis	1
East Fife v Morton	2
Hamilton v Forfar	1
Montrose v Queen Pr.	x(1)
Stranrear v Cowdenbeath	1

Itumọ Alọ

1 Ibẹrẹ.
2 Ọṣun.
3 Obẹrẹ.
4 Okẹrẹ.
5 Abọṣọ.
6 Awẹrẹ.
7 Ọja ofurufu.
8 Ọyan.
9 Ibọn.
10 Ṣagba.
11 Aṣalẹ.
12 Adire.
13 Koko, "Court".
14 Ikoko ati ina.
15 Ọja ọna.

Irohin Yoruba

Ọmọ ọdun mẹwa di abiyamọ

Aiye nlọ enia nto, ọmọ ọdun mẹwa ni ilu Chicago nreti a ti di abiyamọ ni nkan bi ọsẹ meji si,

Omidan yi, eniti awọn obi rẹ ti kọ ara won silẹ wa ni ile iwosan nisisiyi nibiti onisegun rẹ ti sọ fe "ara re nya daradara". Omidan na si ti so pe ọmọ ọdun meriedinlogun ni baba ọmọ na ti on ko iti bi.

Olukọ rẹ ni ile ẹkọ ti nwọn pejọ si ti o ti ṣe akiyesi oyun na ti awọn ọga ile-ẹkọ na si mu lọ si ile iwosan ni bitti onisegun ti ṣe ayẹwo oyun na.

Onisegun rẹ sọ pe "Nigbati on so fun re yio bi ọmọ. o gbọju soke o si so pe ọ nitoto ni pe on yio bi ọm."

Omidan na wa ninu yara rẹ nisisiyi ti o si nge awọn ọmọlangidi lnu iwe, o nṣọkun kikoro, o si nkanu papa.

ỌDARAN DAKU

OLOYE OBAFEMI AWOLOWO

ỌJỌ AWỌLE DE

IROHIN ti bere si kan wa leti lemọlemọ pe laisi aniani gbigbọ ọjọ kotemilọrun ti Oloye Awolowọ ati awọn ẹnia metadinlogun miran ti adajọ Ogbeni G. S. Ṣowemimọ gbe ṣẹwọn ninu ọsu kẹsan odun to koja lori ẹsun iditẹ mọ ijọba ti nwọn ka we won lọsẹ yio waiye ninu osu ti mbọ ti ise osu keji odun yi.

Fyi di mimọ fun onirohin wa lati ẹnu ọgbeni sikiru Shitta-Bey okan ninu awọn agbejoro ninu ẹjọ kotemilorun na, lẹhin ti o ti ba Oloye Awolọwọ jiroro lori ejọ na logba ẹwọn l'Oko fun bi isẹju mẹdogbon ni ọjọ Uti ti ise ọjọ kerinlelogun osu kini odun yi.

Ogbeni Shitta-Bay ti o ri Oloye Obafẹmi Awolọwọ ni dede agogo mokanla koja isẹju mẹdogun ni Ogba ẹwọn sọ fun onirohin wa pe, "Oloye Awolọwọ wa digbidigbi bi o ti wa tẹlẹ ri."

Ogbeni Shitta-Bay wa so siwaju pe, Oloye Awolọwọ so pẹlu ireti kikun pe on yio bori ninu ejọ kotemilorun na.

MEGIDA
MANJE BI IGANJ
Fun Otutu, Iko Efori, Osinmu Ofun didun, Lakoreqbe, Iba, Eeti, Akpalori, Imoria, Kokoro Le apa Oju Ogbe Ero ipe kan Fun Itowo
MEGIDA Wa Kakiri Sobu. Asi nta ni
MEGIDA COY. Box 882 Lagos.

Ile Ẹjọ daru

Ọrọ di bi o ko le lọ, yaṣe fun mi ni ile ẹjọ giga kan ni Owerri ni aipẹ yi nigbati ọkunrin kan ti nwọn fi ẹsun ipanle kan ṣubu, ti o si daku ninu apoti ẹlẹjọ lehin waketi mẹfa ti nwon ti nfi eri wa ọrọ lenu re wo.

Lẹhin wakati mẹfa gbako ti nwon ti nfi ọrọ wa lẹnu wo ni ọwọ imira ba bere si tẹẹ. Adajọ wa pase wipe ki nwọn gbe ijoko fun lati joko sugbọn odaran na fonmu mọ adajọ lọwọ. Ko to bi isẹju melo kan lẹhin eyi, ti odaran fe ṣanlẹ, o si daku gbọnin Bi o ti nyile gbiri ni, o npooka iku.

Adajọ wa wi fun odaran na pe "ko si ohun ti o le se ti yio dun mi duro lati se ise mi. Pẹnu re mọ, ki a maa ba ise lọ."

Bi odaran ti kọ si adajọ lẹnu lati dide ni adajọ ba fẹẹwu lọ, ti awọn ọlọpa si wọ odaran na kuro ninu apoti irojọ fun gbigbe ẹjọ na ni ọjọ iw ju.

Odua *kọ* Ọlọfin

(Lati oju ewe kinni)

J. A. Olunla Oloye Alebiagọ, Ogbeni D. S. Ola Onabade, Ogbeni C. Oladipo Odunsi, Ogbeni J. B Sokunbi Ogbeni O. A. Adedeji (babaleje), Eniowo J. A. Akinyemi, Ogbeni R. A. Awobiyi, Ogbeni J. A. Okusati Ogbeni R. A. Siyanbola.

Akinjide

(Lati ọju ewe kinni)

oruko ẹya kan si ekeji ti mu isina ba opọlọpọ sugbon fifi opin si orisirisi eya nitori ara eni je ipada sẹhin ti o se enia ni iyanu gẹgẹbi ọfa olọro lori awon ti oran na kan lati dabaru ohun ti o fa ikunsinu ati ijangbon."

IDADURO

Oloye R. A. Akinyemi asiwaju apapọ egbe ọdọ Okpara Brigade ti kesi b ba egbe Alakukọ olotu Ijọba Ipinle Ila Orun Nijiria, Dokita M. I. Okpara lati da akawe Igbimọ egbe Alakukọ Ipinle Iwo Orun, Ogbeni R. O. A. Akinjide duro fun titẹmbelu ipinnu igbimo apapo egbe na.

Ni kete ti Oloye Akinyemi se ikede yi ni Ogbeni S. L. A. Fajinmi, igbakeji asiwaju egbe Okpara Brigade Ipinle Iwo-Orun so pe on kuro ninu egbe na, o ni ikede asiwaju egbe na ko tu iyi kun un.

Ninu ikede ti Ogbeni Fajinmi so pe: "ko si were na" ti yio ta ojo ibi rẹ nito i koko egbe nitori awon ohun ti nṣẹlẹ ninu iselu jakejado orilẹ-ede Naijiria.

Awon egbe Alakeke (Zikist Movement) ti fi tokantokan gba ipinnu Igbimọ Apapọ egbe Alakukọ lori titu ti nwon tu Igbimọ egbe na ti Ibadan ka.

AGBAJE SUBU

(Lati oju ewe kinni)

ogba fun egbe na.

Ninu ọrọ rẹ lori bi nwon ti se daduro, o ni "O da mi loju gbangba pe, Oluwa yio dajọ. Inu awon ọta mi le ma dun si ohun ti o ṣẹlẹ si mi yi, ki awon ọrẹ ati alatilehin mi ma ba nuje sugbon bi oni ba koro, ọla le dun, ni tiemi, ohun ti o sele si mi yi, mo ka kun ibukun nlanla, pelu opọlọpọ ọpe ni mo fi fi ipo Minista Alakoso eto Irohin yi sile. Mo si tun dupe lọwọ awon alabasisepo mi fun ifowosowopo sise pelu mi ati imoran ti nwon fun mi nigbati mo wa lenu ise, nko ni gbagbe enikeni ninu won laika. Mo si fe fi ọrọ mi mọ bayi na nitoripe awon egbe mi nran mi lọ si Ibini nipa ọrọ ibo agbedemeji Ipinle Iwo Orun.

Ogbeni R. O. Akinjide ti on pelu Oloye Agbaje jo nfa kanrangbon paapa so pe. on ko le so ohunkan nipa oro idaduro Oloye na nitoripe ise on ni on dojuko nisisiyi.

Nigbati nwon fi oro wa oro lenu Ogbeni Akinjide wo pe, "Nje ki I se rogbodiyan ti o mbe larin egbe ni o fa idaduro Oloye Agbaje?" o ni, idaduro re ko papomo oro rogbodiyan ti egbe rara.

Egbe "Southern Peoples' Congress" Ipinle Iwo Orun ni, idaduro Oloye Agbaje yio tun da nkan miran sile ni Ipinle yi.

Ogbeni Lana ti ise akowe agba egbe na tun so pe, itan ojo miran ni yio je fun awon eniatoripe ipinle yi ni nwon ti kọkọ da minisita kan duro ni agandan rangbon bayi. O ni o yeki Olotu Iwo Orun le fi egun otolo to oro na nitor pe asiko yi ni irepo se pataki ni Ipinle na.

Egbe Alakukọ ti se ipinnu lati ma san owo osu Oloye Majeed Agbaje ti o ngba gẹgẹbi alakoso nigbati o wa ninu Ijọba ati pe awon yio tun pese ẹkọ ayọkẹlẹ ti oba ipo re mu fun.

Awon Igbimo Ile asofin agba Naijiria ati awon omo Ile Igbimo Asofin be Ile Asofin London wa gegebi alejo egbe awon olugbimo awon orile ede ti o nba Ile Cagesi se pọ lehin ti nwon jeun osan pelu awon Ile Igbimo Asofin apesi nwon koja lọ si Ile Igbimo Asofin apesi lati, so bi awon ti nba nse lọ si.

Aworan oke yi ni si Omidan J. an Vickers nigbati o nba awon enia ti o wa lati owo osi si owo otun soro, gẹgẹbi won ni Ogbeni S. W. Kalubya Igbakeji Alaga Uganda Ogbeni P. O. Ekke ati Ogbeni D. M. Obolagunte.

Dear Reader!
let us introduce you (and your family!) to the
Remarkable Renault-4

* 845cc 32 B.H.P More than 70 M.P.H.
* Space for a family of five including their luggage.
* Never needs greasing or water.
* Gets over 47 m.p.g.
* Turns in 28ft. circle.
* Independent 4-wheel suspension.
* Child-proof locks on the three rear doors.
* Fully synchromesh gearbox.
* 6-month guarantee, without mileage limitation.

* Price Ex-Lagos £575 *

ASK FOR A DEMONSTRATION NOW AT
LEVENTIS MOTORS LTD.
LAGOS, APAPA, EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, P.HARCOURT & ABA.

RENAULT 4

ublished by the Eastern Post Limited, Elephant House 214 Broad Street, Lagos and printed for them by the African Press Ltd, P. O. Box 78, Ibadan, Editor: E. O. OLOFIN, c/o 98, Shita Street, Ibadan